# Ipò Àṣà Nínú Ìṣèlú àti Ààbò Orílẹ̀-Èdè Nàìjíríà

**Gòkè Àlàmú**
*Ẹ̀ka Ẹ̀kọ́ Ìmọ̀ Ẹ̀dá-Èdè àti àwọn Èdè Ilẹ̀ Áfíríkà*
*Yunifásitì Ìbàdàn*

**Àṣamọ̀**

Nínú iṣẹ yìí, ohun tí a ó gbéyẹ̀wò ni ipa tí àṣà kó nínú ètò ìṣèlú àti ààbò orílẹ̀ Nàìjíríà. Ọ̀nà márùn-ún ni a pín iṣẹ́ náà sí. Abala kìnínní dálérí oríkì àṣà. Níbí yìí, a ṣe agbéyẹ̀wò oríkì mẹ́ta tí àwọn onímọ̀ fún àṣà. Àwọn oríkì yìí ni a fi ṣe àtẹ̀gùn fún ìtumọ̀ tí a fún àṣà nínú iṣẹ́ yìí. Ní abala kejì, a ṣe àtúpalẹ̀ àwọn ọ̀nà tí àwọn Yorùbá fi ń ṣe ìlú láyé àtijọ́ nípa ṣíṣe àmúlò àṣà wọn. A ṣe èyí láti fi ọ̀nà tí à ń gbà ṣe ìlú láyé àtijọ́ wé ti òde òní èyí tí ìpele kẹta dálérí. Ní ìpele kẹrin, a ṣe àgbéyẹ̀wò àwọn ohun tí a lè ṣe láti mú àṣà wa lọ́kùn-ún-kúndùn àti àwọn ọ̀nà tí àṣàYorùbá èyí tí ó dálérí ọmọlúàbí lè gbà mú kí ìṣèlú àti ààbò orílẹ̀ wa dánmọ́rán sí i. Ìkádìí iṣẹ́ yìí ni a fi orí ìpele karùn-ún sọ.

## 1. Ìfáárà

Àṣà tí a fẹ́ sọ̀rọ̀ nípa rẹ̀ nínú iṣẹ́ yìí ni àṣà Yorùbá. Ìdí rẹ̀ ni pé ìmọ̀ àṣà yìí ni oǹkọ̀wé nì jùlọ. Àmọ́ ṣá, a lè lo àṣà Yorùbá gẹ́gẹ́ bí àwòkọ́ṣe fún àwọn àsà ilẹ̀ Nàìjíríà yòókù. Gẹ́gẹ́ bí a sì ti mọ̀, káríayé ni àṣà jẹ́. Kò sí ìlú tàbí orílẹ̀ kan tí kò ní àṣà tirẹ̀

ṣùgbọ́n àwọn àṣà yàtọ̀ láti agbègbè kan tàbí láti ìlú kan sí òmíràn. Láàrin ilẹ̀ káàárọ̀-oò-jíire pàápàá, a rí ìyàtọ̀ nínú àwọn àṣà díẹ̀ láàrín ìletò sí ìletò àti láàrin ẹ̀ka Yorùbá kan sí èkejì. Kí wá ni ìtumọ̀ àṣà?

Ẹ jẹ́ kí á wo oríkì mẹ́ta tí a fún àṣà.

i) *The set of distinctive spiritual, material, intellectual and emotional features of a society or a social group, encompassing, in addition to art and literature, lifestyles, ways of living together, value systems, traditions and beliefs (UNESCO 2002:2).*

   Àkójọpọ̀ àwọn àbùdà àdámọ̀ adálérí ẹ̀sìn, oun, iṣẹ́ ọpọlọ àti àwọn ìmọ̀sílára ti àwùjọ kan. Lára rẹ ni ọ̀nà ìgbéayé, ọ̀nà ìbágbépọ̀, ìgbàgbọ́, àṣà lítíréṣọ̀ àti iṣẹ́ ọnà àwùjọ bẹ́ẹ̀

ii) *It is the established pattern of behaviour among a people. It is an all embracing and heterogenous concept that encompasses every aspect of a man's life and experiences. It includes everything that makes man what he is, as well as the heritage he possesses. It finds expression in his religion, language, philosophy, music, dance, drama, architecture, political organisation, technology and so on. Everything made by man is culture; everything created by God is nature (Àjàyí 2005:1).*

   Ọ̀nà àgbékalẹ̀ ìhùwàsí àwùjọ kan. Àwọn àkóónú àṣà pọ̀ rẹpẹtẹ, wọ́n sì dalérí gbogbo ohun tó rọ̀mọ́

ìrírí ẹ̀dá àti ìgbèayé rẹ̀. Ó dàlérí ẹ̀sìn, èdè, ijó, eré-oníṣe, ìṣèlú àti bẹ́ẹ̀bẹ́ẹ̀ lọ. Gbogbo ohun tí ẹ̀dá dá ni àṣà; gbogbo ohun tí Ọlọ́run dá ni ẹ̀dá.

iii) *Culture is God's own way of organising His people all over the world in cohesive groups, each with its own peculiar skills and knowledge. God knows the minutest aspect of every culture. Religion is just an aspect of culture. Religion is intended to ensure that the foundations of culture, the humane qualities of man remain stable. Culture it is that makes the man. As a matter of fact, if your culture has not socialised you into the acceptable standards of accountability, and so on, there will be no foundation on which any religion can build. In this regard, being born again really means going back to your God-given culture to learn how to be a good person (Ìsọ̀lá 2010: 29).*

Àṣà ni ọ̀nà tí Ọlọ́run gbà ṣe ètò àwọn ẹ̀dá ọwọ́ rẹ̀ ní gbogbo àgbáyé sínú ẹgbẹ́ kọ̀ọ̀kan; èyí tí ó ní ìmọ̀ tirẹ̀ . Ọlọ́run mọ gbogbo ọ̀rínkinniwín àṣà kọ̀ọ̀kan. Ẹ̀sìn jẹ́ apá kan nínú àṣà. Orí ẹ̀sìn ni àṣà dúró lé. Àṣà ní ó fun ni ní ìwà. Bí àṣà wa kò bá sì kọ́ ni ní ọ̀nà òótọ́, kò sí ohun kan tí a lè gbé àṣà kà. Ní ìdí èyí, dídi àtúnbí túmọ̀ sí pípadà sí àṣà tí Ọlọ́run fún wa láti kọ́ bí a ṣe lè jẹ́ ọmọlúàbí.

Àlàyé tí a fẹ́ ṣe lórí àwọn oríkì òkè yìí ni pé: àṣà dálérí ẹ̀sìn, ìgbàgbọ́, ìmọ̀ ìjìnlẹ̀, èrò, àti àwọn ohun ìmọ̀sílára àwùjọ kan. Lára àwọn ohun mìíràn tó rọ̀mọ́ àṣà ni èdè àwùjọ kan, orin àti ijó wọn, iṣẹ́ ọnà, lítíréṣọ̀, ọ̀ṣèlú ṣíṣe, ọ̀nà ìkọ́lé àti bẹ́ẹ̀ bẹ́ẹ̀ lọ.

Gbogbo ọ̀nà ìgbéayé àwùjọ kan ni àṣà jẹ́. Gbogbo ohun tí ẹ̀dá dá tàbí tí ẹ̀dá ń ṣe ni ó rọ̀mọ́ àṣà. Bí Ìsọ̀lá sì ti sọ, ọ̀nà kan tí Ọlọ́run gbà kó àwọn ènìyàn jọ ní ìṣọ̀rí ìṣọ̀rí, oníkálukú pẹ̀lú ọgbọ́n inú àti ìmọ̀ ni àṣà jẹ́. Kò sí àṣà kan tí Ọlọ́run kò mọ̀. Àṣà ni orísun ìwà rere, òun ni ó ń kọ́ni ní ohun tó dára àti èyí tí kò dára. Ìṣọ̀lá tilẹ̀ sọ pé ìtumọ̀ kí ènìyàn di àtúnbí ni kí ó padà sínú àṣà tí Ọlọ́run fún un kí ó sì lọ kọ́ bí a ti í di ènìyàn rere. Ní àkótán, àwọn oríṣi ọ̀nà tí à ń gbà ṣe nǹkan ní àwùjọ kan ni à ń pè ní àṣà. Ìdí nìyí tí ó fi jẹ́ pé kò sí ohun kan tí à ń ṣe tí a kò lè kà kún àsà bí àpẹẹrẹ: àṣà ìjẹun, àṣà ìwọṣọ, àṣà ìkíni, àṣà ìkọ́lé, àṣà ìnáwó, àṣà ìwòran, àṣà ọ̀rọ̀ sísọ, àṣà ìsọmọlórúkọ, àṣà ìgbéyàwó àti bẹ́ẹ̀ bẹ́ẹ̀ lọ.

Àṣà ṣe pàtàkì fún ìdàgbàsókè àwùjọ, pàápàá àwọn àṣà tí ó jẹmọ́ ìwà híhù àti ìṣesí. Bi àpẹẹrẹ, gbogbo àwọn ìwà tí ó lè mú ìfẹ́ àti àlàáfíà bá àwùjọ ni àwọn àkòónú àṣà ọmọlúwàbí. Ohun tí ó ṣe pàtàkì jù lọ nínú àṣà Yorùbá ni ìwà ọmọlúwàbí. Ìwà ọmọlúwàbí jẹ́ ogo ìran Yorùbá nítorí pé wọn ka ìwà rere sí púpọ̀ (Ògúndèjì 2009: 73). Ìdí nìyí tí Yorùbá fi ń pòwe pé: Ìwà rere lẹ̀ṣọ́ ènìyàn. Lára ìwà rere ni ẹ̀mí ìrẹ̀lẹ̀ àṣà ìbọláfún tàbí ìbọ̀wọ̀fágbà, ìṣòótọ́, ìtẹpámọ́ṣẹ́, ìṣoore, abbl. Ní Ìdàkejì, àwọn ìwà búburú bí i olè jíjà, àìṣòótọ́, ìgbéraga, ọ̀lẹ, ilẹ̀ dídà, ojúkòkòrò, panṣágà, abbl, ni àwọn Yorùbá bu ẹnu àtẹ́ lù. A rí àpẹẹrẹ pàtàkì ìwà rere nínú àwọn òwe Yorùbá bí i:

i) Ẹni tó lórí rere tí kò níwà rere, ìwa rẹ̀ ni yó borí i rẹ̀ jẹ́.
ii) Ìwà lẹwà
iii) Ìwà lòrìṣà, bí a ti hù ú sí ní n gbeni sí

Nítorí ìdí èyí a lè sọ pè ìwà àwùjọ kan ni ẹ̀ka àṣà irú àwùjọ bẹ́ẹ̀. Ìwà àti ìṣesí Yorùbá ni gbogbo àṣà Yorùbá ń ṣàfihàn. Gbogbo wa la sì mọ̀ pàtàkì ẹbí nínú ìdàgbàsókè àwùjọ tàbí orílẹ̀-èdè kan. Ìpìlẹ̀ àti ègé àwùjọ kan ni ẹbí jẹ́. Bí àwọn ẹbí àwùjọ kan bá tí dára tó náà ni àwùjọ náà yóò ti dára tó, tí àlàáfíà àti ìdàgbàsókè yó sì wà. Inú ẹbí kọ̀ọ̀kan ni ọmọlúwàbí wà. Inú ẹbí kọ̀ọ̀kan náà ni àwọn aṣebi ti wạ̀.

## 2. Ìṣèlú àti àṣà láyé àtijọ́ -

Àwọn èniyàn ni ìlú ṣíse tàbí ìṣèlú dálérí. Àwọn èniyàn tí a yàn sípò tàbí dìbò fún ni ó ń ṣe ètò ìjọba. Aṣojú àwọn èniyàn ni wọ́n jẹ́. Àwọn èniyàn sì ti ní ìgbẹ́kẹ̀lé nìnù wọn, wọ́n ti gba ẹ̀rí wọn jẹ́ pé wọ́n kójú òṣùwọ̀n kí wọ́n tó dìbò fún wọn. Àwọn tí ó ń ṣe ètò ìjọba ni adarí ìlú tí a ti fún láṣẹ láti ṣẹ àgbékalẹ̀ oríṣìíṣìí ìlànà tí yóò mú ìdàgbàsókè àti àlàáfíà dé bá ìlú, àwọn olùgbé ibẹ̀ àti àmúṣe àwọn ìlànà náà.

Ní abẹ́ ìjọba tiwa-n-tiwa èyí tí orílẹ̀-èdè Nàìjíríà ń múlò láti ṣe àkóso ìjọba, abala tàbí ìpele mẹ́ta ni ó wà: ìgbìmọ̀ aláṣẹ, ìgbìmọ̀ aṣòfin àti ìgbìmọ̀ ìdájọ́. Orúkọ àwọn ìgbìmọ̀ mẹ́tẹ̀ẹ̀ta yìí ti ṣàpèjúwe iṣẹ́ tí ọ̀kọ̀ọ̀kan ń ṣe nínú ètò ìjọba, ṣùgbọ́n a ti mọ̀ pé

nínú ìgbìmọ̀ mẹ́tẹ̀ẹ̀ta yìí, aṣòfin ni ó jẹ́ aṣojú àwọn ará ìlú jùlọ nínú ètò ìjọba ṣíse nítorí pé láti inú ìjọba ìbílẹ̀ èyí tí ó súnmọ̀ àwọn ará ìgbèríko àti àwọn ará ìlú ni a ti yàn wọ́n.

Àmọ́, ó ní ohun tí adìẹ ń jẹ kí àgbádo tó dé . Yorùbá ti ní ètò ìjọba tirẹ̀ kí ọ̀làjú tó dé. Kò ṣì sí ìyàtọ̀ kan nínú ètò ìjọba Yorùbá yìí àtí èyí tí à ń pè ní tiwa-n-tiwa lóde-òní. Láì déènà pẹnu, nínú gbogbo ẹ̀yà ilẹ̀ Nàìjíríà, Yorùbá ni ó dàbí ẹni pé ó lajú jùlọ  nítorí pé gbogbo ètò ìlú ṣíse tí a mẹ́nu bà lóde òní ni Yorùbá ti ṣe àmúlò fún ìjọba ṣíṣe ní ọ̀pọ̀lọpọ̀ ọdún sẹ́yìn. Ìyàtọ̀ kan tí a lè sọ pé ó wà ni pé nígbà ti ètò ìjọba òde-òní jẹ́ alábala mẹ́ta, alábala méjì ni ti Yorúbá ní ayé àtijọ́. Èyí ni pé àwọn ìjòyè àti ọba ni wọ́n wà ní ìgbìmọ̀ aláṣẹ tí wọ́n sí ń ṣe ètò ìjọba.

Ọba ni olórí ìlú gẹ́gẹ́ bí Ààrẹ ṣe jẹ́ olorí ilẹ̀ Nàìjíríà. Ọbá ní àwọn ìjòyè tó ń ràn án lọ́wọ́ láti darí ìlú. Àwọn ìjòyè yìí ni wọ́n máa ń péjú sí ààfin láti jíròrò lórí àwọn ohun tó ń lọ ní ìlú àti ọ̀nà tí àlàáfíà yóò ṣe jọba kí ìlú fi rọrùn láti gbé fún mùtúmùwà. Ìjíròrò wọn túbọ̀ máa ń dálérí ààbò ìlú àti ìbáṣepọ̀ láàrin ìlú wọn àti àwọn ìlú tí ó yí wọn ká tàbí èyí tí ó wà lábẹ̀ àkóso wọn.

Nítorí ipò tí a fi ọba sí, kì í ṣe pé àwọn ìjòyè yìí máa ń jókòó ti ọba ní gbogbo ìgbà fún  ìjíròrò wọn. Àbọ̀ ìjíròrò wọn ni wọ́n sábà máa ń fún ọba. Ipò ọba àti àwọn ìjòyè rẹ̀ kò yàtọ̀ púpọ̀ sí ìgbìmọ̀ aláṣẹ àti ìgbìmọ̀ aṣòfin ní òde oní. Ìyàtọ̀ díẹ̀ tó wà níbẹ̀

ni pé láyé àtijọ́, ọba àti àwọn ìjòyè rẹ̀ náà ni ó ń ṣe ètò ìdájọ́. Kò sí ìgbìmọ tí ó dáwà tí ó ń ṣe ètò ìdájọ́ gẹ́gẹ́ bí ó ṣe wà lónìí.

Bí ìgbìmọ̀ aṣòfin ṣe lè rọ olórí orílẹ̀-èdè lóyè bẹ́ẹ̀ náà ni àwọn ìjòyè ní agbára lábẹ́ òfin láti rọ ọbakọ́ba tó bá ṣìwàhù lóyè. Bí àpẹrẹ, ìtàn sọ fún wa pé ní Ọ̀yọ́-Ilé, àwọn Ọ̀yọ́mèsì ní kí Aláàfin Awólẹ̀ lọ ṣí igbá lẹ́yìn ìgbà tí Àfọ̀njá pinnu láti gbógun tí Ọ̀yọ̀-Ilé pẹ̀lú ìfọwọ́sowọ́pọ̀ Baṣọ̀run Àṣàmù. (Oguntomisin 2002:228-9).

Dípò tí Àfọ̀njà (Ààrẹ-Ọ̀nà Kakaǹfò) ìbá fi gbógun ti Ìwèrè-Ilé níbi tí Aláàfin Awólẹ̀ rò pé yóò kú sí, níṣe ni ó kọjú ogun sí Ọ̀yọ́-Ilé, b65 ni pẹ̀lú ìrànlọ́wọ́ Baṣọ̀run Àṣàmù wọ́n pa àwọn ẹ̀ṣọ́ ààfin. Nígbà tí àwọn Ọ̀yọ́mèsì sì rí i pe Àfọ̀njà àti àwọn ènìyàn rẹ̀ tí ń ṣẹ́gun, wọ́n ránṣẹ́ sí Aláàfin Awólẹ̀ kí ó lọ ṣígbá. Èyí ni ìgbà àkọ́kọ́ tí àwọn ológun yóò gba ìjọba ní ilẹ̀ Yorùbá. (Oguntomisin 2002:229).

Lóòótọ́, ofin ìṣàkóso ilẹ̀ Yorùbá kò ní àkọsílẹ̀ láyé àtijọ́, ṣùgbọ́n gbogbo ará ìlú ní ó mọ àwọn ìwà tó lòdì sófin. Wọ́n sì mọ ìyà tó tọ́ sí arúfin. Bákan náà ni àwọn òfin yìí kò fàyè gba ọba láti ní àṣẹ tí kò lódiwọ̀n tàbí agbára apàṣẹ-wàá. Lóòótọ́ ọba aláṣẹ ni à ń pe ọba ṣùgbọ́n ó níbi tí agbára tàbí àṣẹ ọba mọ. Àwọn ìjòyè wà tí ó lè ká ọba tí ó bá fẹ́ ṣi agbára lò lọ́wọ́kò (Oguntomisin 2002:226). Oríṣiríṣi orúkọ ni à ń pe àwọn ìgbìmọ̀ ìjòyè yìí láti ìlú tàbí agbègbè kan sí òmíràn ní ayé àtijọ́. Bí

àpẹẹrẹ: Ọ̀yọ́mèsì (ìlú Ọ̀yọ́), Ìwàrẹ̀fà (Ifẹ̀ àti Èkìtì), Ìlámùrẹ́n (Ìjẹ̀bú), Ògbóni (Ẹ̀gbá), àti bẹ́ẹ̀ bẹ́ẹ̀ lọ.

Ní ti ààbò ìlú, oríṣiríṣi ọ̀nà ni Yorùbá ń gbà dáàbòbo ìlú ní ayé àtijọ́. Àwọn ẹ̀ṣọ́ ìlú wà tó jẹ́ pé iṣẹ́ wọn ni láti rí i pé àwọn ṣe ìfẹ́ ọba àti ìjòyè láti jẹ́ kí àlàáfíà wà ní ìlú. Àwọn wọ̀nyí ni a le fi wé ọlọ́pàá ní òde-òní. Bákan náà ni àwọn ọmọ-ogun wà láti dáàbòbo ìlú lọ́wọ́ ìlú mìíràn tí ó fẹ́ gbógun tì wọ́n tàbí láti gbógun ti ìlú tí ó bá ṣe àfojúdi sí wọn. Gẹ́gẹ́ bí a ti rí i nínú àkọsílẹ̀, ní ìlú Ọ̀yọ́, Ààrẹ-ọ̀nà-Kakaǹfò, olórí ọmọ ogun kò gbọdọ̀ kùnà láti borí ogunkógun láàrin oṣù mẹ́ta, bíbẹ́ẹ̀kọ́ ó níláti lọ ṣígbá (Oguntomisin 2002:229).

Oríṣiríṣi ọ̀nà ni a fí ń jẹ arúfin níyà ní ilẹ̀ Yorùbá. Ìdí tí a fí ń fi ìyà jẹ arúfin ni láti jìyà ẹ̀ṣẹ̀ rẹ̀ àti láti kìlọ̀ fún àwọn tí ó bá tún fẹ́ hu irú ìwà bẹ́ẹ̀. Ìjìyà wúwo ju ara wọn lọ, wọ́n sì dálérí bí ẹ̀ṣẹ̀ arúfin náà ṣe wúwo tó. Bí àpeẹrẹ, bíbẹ́lórí ni à á bẹ́ apànìyàn lórí, a sì ń fi àwọn arúfin mìíràn rúbọ. Síwájú sí i, kò sí ìlú Yorùbá ní ayé àtijọ́ tí kò ní ojú-ọjà. Yàtọ̀ sí pé à ń lo ọjà fún kátàkárà tàbí fún eré ìdárayá, à ń lo gbàgede ọjà bákan náà gẹ́gẹ́ bí i ibi tí a ti ń fi arúfin ṣẹ̀sín tàbí fi ìyà jẹ arúfin (Ògúndèjì 2006:8-9). Ohun ìtìjú sì ni fún irú arúfin bẹ́ẹ̀ àti ìdílé rẹ̀. Bi àpẹ̀ẹrẹ̀, nínú *Baṣọ̀run Gáà*, ojú-ọjà ni a ti fi Gáà ṣẹ̀sín, tí a sì fi ìyà jẹ ẹ́:

Bó o láyà o ṣìkà
Bó o rántí ikú Gáà o sòótọ́ (o.i 140).

Ọ̀nà mìíràn tí Yorùbá fi ń dáàbòbo ìlú láyé àtijọ́ ni mímọ odi yí ìlú ká. Ẹnu odi ìlú ni wọ́n ti í lé ọ̀tá sẹ́yìn ní àsìkò náà. Ibẹ̀ náà sì ni wọn yóò ti mọ̀ bí àlejò kan bá wọ ìlú.

Ní ilẹ̀ Yorùbá láyé àtijọ́, ọ̀pọ̀lopọ̀ ni ó gbe iwà ọmọlúàbí wọ̀. Àgbẹ̀ ṣíṣe kò jẹ́ kí ebí pa àwọn ènìyàn. Gbogbo olórí ẹbí ni màa ǹ dáko tí àwọn aya àti ọmọ sì máa ń ràn wọ́n lọ́wọ́. Yorùbá sì bọ̀ wọ́n ní bí oúnjẹ bá ti kúrò nínú ìṣẹ́, ìṣẹ́ bù ṣe. Láyé àtijọ́, ọ̀pọ̀lọpọ̀ ènìyàn ló ní ìtẹ́lọ́rùn. Bi kò tilẹ̀ sí owó, wọn a máa sá fún ohun tó le ba orúkọ ìdílé jẹ́. Wọn a ní *orúkọ rere sàn ju wúrà àti fàdákà lọ*. Ẹ̀mí ìpamọ́ra wà. Ọ̀pọ̀ ni kò lé afẹ́ ayé. Ìrọ̀rùn, àlàáfíà, ẹ̀mí ìbágbépọ̀ àti ìbáṣepọ̀ wà, mọ̀lẹ́bí ṣíṣe wà, oríṣiríṣi àṣà ìranraẹnilọ́wọ́ wà. Láyé àtijọ́, *ẹnìkan ní í bímọ, igba ojú ní í wò ó*. Yorùbá gbà pé a gbọ́dọ̀ fọwọ́sowọ́pọ̀ láti tọ́ ọmọ kí ọmọ náà ba à lè yanjú.

Lákòótán, àwọn òrìṣà ń dáàbòbo ará ìlú, à sì ń tọ̀ wọ́n lọ fún ohun tó bá rújú ní ìlú. Yàtọ̀ fún ẹnìkọ̀ọ̀kan tàbí ìdílé, àwọn tí wọn ń ṣe ìlú (ọba àti ìjòyè) máa ń tọ ifá lọ fún ìmọ̀ràn. Àwọn òrìṣà mìíràn bí i Ṣàngó, Ògún, Èṣù, àti bẹ́ẹ̀ bẹ́ẹ̀ lọ sì máa ń fi ìyà jẹ ẹlẹ́ṣẹ̀ lẹ́ṣẹ̀kẹṣẹ̀. Èyí sì mú kí àwọn ènìyàn ní ìbẹ̀rù, kí wọ́n sì sá fẹ́ṣẹ̀ tàbí iṣẹ́ ibi (Abímbọ́lá 1977:1).

## 3. Lóde òní

A ti sọ lókè pé ìpele mẹ́ta ni ìjọba tiwa-n-tiwa tí à ń lò fún ètò ìjọba. Èyí ni ìgbìmọ̀ aláṣẹ, ìgbìmọ̀ aṣojúṣòfin àti ìgbìmọ̀ ìdájọ́. Ojúṣe ìjọba ni láti máyé dẹrùn fún àwọn arà ìlú nípa pípèsè àwọn ohun bíi iná ẹ̀lẹ́tíríìkì, omi ẹ̀rọ̀, títì tó dára, ìwòsàn tó dájú, iṣẹ́ fún àwọn ọ̀dọ́ àti pàápàá jùlọ ààbò tó múnádóko. Nítorí pé láìsí ààbò tó múnádóko, àlàáfíà, ìrẹ́pọ̀ àti ìfọkànbalẹ̀ kò lè jọba lórílẹ̀-èdè kan. A lè sọ pé nítorí ìjọba ilẹ̀ Nàìjíríà kò pèsè ààbò tó dájú ní ìjínigbé, ìdigunjalè, àti ìpànìyàn fi pọ̀ ní ìlú. Àwọn alákatakítí ẹ̀sìn ti gbòde kan, ó sì dàbí ẹni pé apá ìjọba kò ká wọn.

Gbogbo wa ni a mọ̀ pé ní abẹ́ ìjọba tiwa-n-tiwa, ojúṣe àwọn ọlọ́pàá ni láti mójútó ààbò ìlú àti mú arúfin wá sí ìdájọ́. Ààbò àwọn ará ìlú ni ọlọ́pàá máa ń mójútó nígbà tí àwọn ọmọ ogun yòókù sì wà fún ìdáàbòbò ìlú lọ́wọ́ ìlú mìíràn àti fún ogun. Sùgbọ́n lóde òní, èyí kò rí bẹ́ẹ̀ ní ilẹ̀ Nàìjíríà. Lójoojúmọ́ ni à ń ri àwọn ọmọ ogun (sọ́jà) lójúu pópó. Ohun tí èyí túmọ̀ sí ni pé ogun abẹ́lé wà ní Nàìjíríà. Ìjọba pàjáwìrì tí ìjọ̀ba àpapọ̀ ṣe àgbékalẹ̀ rẹ̀ ní Ìpínlẹ̀ Yobe, Adamawa àti Borno jẹ́ àpẹẹrẹ. Ohun tí ó sì fa èyí ni àìní ìjọba tó dára, tó sì kójú òṣùwọ̀n. Dípò kí ọ̀nà láti máyé dẹrùn fún àwọn ará ìlú jẹ àwọn tó ń ṣe ìjọba lógún, ìwà wọ̀bìà, olè àti ojúkòkòrò tí wọ̀ wọ́n lẹ́wù; ó ti di bárakú. Àpò ara wọn ni ọ̀pọ̀ olóṣèlú mọ̀. Àpò ara wọn ni wọ́n ń pa owó sí. Àwọn

ará ìlú ò mọ iye tí wọn ń gbà. Òótọ́ ṣọ̀wọ́n nínú ètò ìjọba àfi ẹ̀tàn. Ọwọ́ àwọn kà-ǹ-da ọlọ́pàá tí o yẹ kó tẹpẹlẹ mọ́ pípa òfin ilẹ̀ wa mọ́ ni gbogbo ìwa burúkú ilé ayé yìí wà. Gbogbo wa ni a mọ̀ pé ọ̀pọ̀ nínú àwọn ọlọ́pàá kì í ṣe ọ̀rẹ́ ará ìlú. Ọ̀tá ará ìlú ni wọ́n jẹ́. A sì mọ̀ pé ìlú tí kò bá ti sí òótọ́ kò lè sí ìdàgbàsókè, ìrẹ́pọ̀, àti àlàáfíà ní irú ìlú bẹ́ẹ̀. Ọ̀pọ̀lọpọ̀ ìgbà ni a ti ṣàkíyèsí pé orísìí òfin méjì ni ó wà ní ilẹ̀ Nàìjíríà: òfin fún olówó tàbí fún àwọn tí ó wà ní ipò àti òfin fún mẹ̀kúnnù. Bí ènìyàn kan bá ṣe ní owó tó ni ó le ṣe ohun àṣegbé tó wù ú.

Kí wá ni àwọn ohun tí ó ń fa ìwà ọ̀daràn àti àìsí ààbò? Àwọn okùnfà wọ̀nyí pọ̀. Ìmọtaraẹninìkan, àìnítẹ̀ẹ́lọ́rùn tàbí ọ̀kánjúwà àti àìríṣẹ́ṣe; borí gbogbo èyí ni ìṣẹ́. Yorùbá bọ̀ wọ́n ní Adébipani kì í ṣọ̀rẹ́ ẹni. Ìjọba tó yẹ kó máyé dẹ̀rùn fún àwọn ará ìlú kò pèsè iṣẹ́ pàápàá fún àwọn ọ̀dọ́ abarapá. Ọ̀pọ̀lọpọ̀ ọ̀dọ́ ni kò ríṣẹ́ ṣe tí kò sì ní ìrètí àti sùúrù pé ọjọ́ ọ̀la yóò dára. Irú àwọn ọ̀dọ́ báyìí, pàápàá èyí tí a kò bá fi ìwà ọmọlúwàbí kọ́, tí kò sì wá láti ilé tó dára ní í dojú ìjà kọ àwùjọ, tí wọ́n sì í di adigunjalè, onífàyàwọ́, agbégbòogi àti ajínigbé. Bí ará iwájú ò bá sì mọ̀ọ́rìn, ìgbẹ́ lará ẹ̀yìn ń wọ̀. Ẹ̀hónú ni ọ̀pọ̀ ọ̀dọ́ ń fihàn tí wọ́n fi ń hu ìwà ìbàjẹ́. Ipasẹ̀ àwọn òṣèlú wa ni ọ̀pọ̀ ọ̀dọ́ ń tọ̀. Ìṣẹ́ ń ṣẹ́ ọ̀pọ̀ ará ìlú ní ìlú tí ó ń ṣàn fún wàrà àti fún oyin.

Báwo ni ìwà àwọn tó ń ṣàkóso ilẹ̀ wa ti rí? Irú ìwà wo ló wà lọ́wọ́ wọn? Gbogbo ìwà ìbàjẹ́ ayé yìí ni ó kún ọwọ́ ọ̀pọ̀lọpọ̀

àwọn òṣèlú wa. Ọ̀pọ̀lọpọ̀ nínú wọn ni olè, àmọtaraẹninìkan, olójúkòkòrò, apàniyàn ati bẹ́ẹ̀ bẹ́ẹ̀ lọ. Bí a ṣe rí Gómìnà tó kówó ìlú jẹ tí ó sì wà látìmọ́lé ní ìlú òkèrè (James Ibori) ni a rí aṣojúṣòfin tó gba ribá (Farouk Lawan). Dípò kí wọ́n ṣe àwọn ohun tí ó lè mú ìdẹ̀rùn bá àwọn ará ìlú, àpò ara wọn ni wọ́n ń pawó sí, tara wọn nìkan ni wọ́n mọ̀. Ìtànjẹ ni wọ́n fi ń bá ará ìlú lò, wọn ò lóòótọ́ lẹ́nu, wọn kò ní ìfẹ́ àwọn tí wọ́n ń jọba lé lórí. Bí àpẹẹrẹ, gbogbo ará ìlú Amẹ́ríkà ni ó mọ iye owó oṣù tí Ààrẹ Barrack Obama àti àwọn olóṣèlú yòókù ń gbà, ṣùgbọ́n èyí kò rí bẹ́ẹ̀ ní Nàìjíríà. Awo ni àwọn olóṣèlú tiwa fi èyí ṣe. Pẹ̀lú owó gọbọi tí wọn ń gbà, ìnira ni ó máa ń jẹ́ fún wọn tí òṣìṣẹ́ bá bèèrè fún ẹ̀kúnwó, bí wọ́n bá sì gbà láti san an, ó dìgbà tí òṣìṣẹ́ bá da iṣẹ́ sílẹ̀ kí wọn tó rí irú owó bẹ́ẹ̀ gbà. Ìṣọ̀lá (2013:3) tilẹ̀ kó gbogbo rẹ̀ já:

> Ohun tí ó tún wá ba gbogbo rẹ̀ jẹ́ ni ti àwọn aṣaájú olóṣèlú wa tí wọn kò ní àǹfààní àtikọ́ ìwà ọmọlúàbí tí ó yẹ kí àṣà ti kọ́ wọn. Wọn kì í ṣolóòótọ́, wọn kò ṣe é gbẹ́kẹ̀lé, wọn kò le dáàbò bo ẹ̀tọ́ òṣìṣẹ́ ọmọ-ilẹ̀ wọn ní ìlú tiwọn.

Láti gbé ayé ìdẹ̀rùn, ọ̀pọ̀ ará ìlú ni ó ń pèsè omi fúnra wọn pẹ̀lú gbígbẹ́ kànga ìgbàlódé, tàbí pèsè iná nípa rírà ẹ̀rọ tí ó ń pèsè iná. Láyé àtijọ́, a mọ̀ pé ibikíbi tí a bá ti rí ògiri gíga, ọgbà ẹ̀wọ̀n nìyẹn, ṣùgbọ́n lóde òní ọ̀pọ̀lọpọ̀ wa lati wà nínú ọgbà ẹ̀wọ̀n tí a

pèsè fún ara wa nípa mímọ ògiri yí ilé wa ká nítorí kò sí ààbò tó múnádóko.

Gẹ́gẹ́ bí a ṣe sọ ṣaájú, ohun tí ó ṣe pàtàkì jù lọ nínú àṣà Yorùbá ni ìwà ọmọlúàbí. Àwọn òbí níláti kọ́ àwọn ọmọ wọn ní ìwà yìí, wọn kò gbọdọ̀ dúró de olùkọ́ nìkan pàápàá láyé òdeòní tí ètò ẹ̀kọ́ wa ti foríṣọ́pọ́n, tí ìjọba ń wá ọ̀nà láti dá ẹ̀kọ́ àwọn èdè ilẹ̀ abínibí ní ilé-ìwé dúró. Lóde òní, èdè àjèjì ni a fí ń kọ́ ọmọ láti ìbẹ̀rẹ̀ ẹ̀kọ́ dé òpin Yunifásitì ní orílẹ̀-èdè Nàìjíríà. Ìjọba tẹpẹlẹ mọ́ kíkọ́ ẹ̀kọ́ sáyẹ́ńsì àti ìmọ̀ ẹ̀rọ tàbí tẹkinọ́lọ́jì ju àwọn ẹ̀kọ́ tó rọ̀mọ́ ìbágbépọ̀ ẹ̀dá àti àwùjọ lọ. Èyí sì ni ọ̀kan lára ohun tó ń fa ìṣòro fún Nàìjíríà nítorí pé ọ̀pọ̀ àwọn ọmọ tó ń kẹ́kọ̀ọ́ gboyè pàápàá nínú ìmọ̀ sáyẹ̀ǹsì, ní kò ní ẹ̀kọ̀ nípa ọ̀nà ìbágbépọ̀. Nínú àwọn ìtàn àti lítíréṣọ̀ wa ni a ti lè kọ́ nípa ọ̀nà ìbágbépọ̀ tí ó lè mú àlàáfíà wá kì í ṣe nínú sáyẹ̀ǹsì. Kì í ṣe pé a ní kí ìmọ sáyẹ̀ǹsì tàbí tẹkinọ́lọ́jì jó àjórẹ̀yìn nítorí pé wọ́n wúlò lọ́pọ̀lọpọ̀ fún ìdàgbàsókè ìlú àti pé ìgbà ti yí, ayé ti dáye kọ̀ḿpútà, ṣùgbọ́n tí a bá fẹ́ kí àwùjọ wa dára kí ó sì mú àlàáfíà wá, ẹ̀kọ́ àwọn èdè abínibí wa náà kò gbọdọ̀ jó àjórẹ̀yìn nítorí pé nínú wọn ni àṣà wa wà; àṣà wa sì ni orísun ìwà rere.

Ní ìgbà díẹ̀ sẹ́yìn, nínú ètò ẹ̀kọ́ wa àti nínú ẹ̀kọ́ èdè Yorùbá ni àwọn olùkọ́ ti ń fi ìpìlẹ̀ ẹ̀kọ́ ìwà ọmọlúàbí lélẹ̀ fún akẹ́kọ̀ọ́. Gbogbo àwọn ewì bí i *Tọ́jú ìwà rẹ, Iṣẹ́ ni òògùn* ì*ṣẹ́*, àti *Kí ni ń o folè ṣe*? (Ọdúnjọ 1961: 2,3,41) ni a fi ń kọ́ akẹ́kọ̀ọ́ ní

ilé-ìwé ayé àtijọ́ tí ó sì ń tọ́ wọn sọ́nà nínú ìgbé ayé wọn. Sùgbọ́n ìbànújẹ́ ló jẹ́ fún wa pé kò sí irú ẹ̀kọ́ tó yè kooro báyìí mọ́. Ọ̀pọ̀ òbí ni kò tilẹ̀ fẹ́ kí ọmọ wọn sọ Yorùbá mọ́. A ti ń sọ àṣà wa nù, iná àṣà wa ti ń jó àjórẹ̀yìn. Àṣà ọ̀làjú ti dé, ayé ti di rúdurùdu. Ọkùnrin kò rí ṣòkòtò wọ̀ mọ́; ọkùnrin ń relé onídìrí; ìyá ò rójú mójútó ilé; ìwé kíkà ni àwọn ọmọ lára; ọmọ ọgbọ̀n ọdún fẹ́ kọ́lé; ọmọ ogún ọdún fẹ́ lo mọ́tò; kò sí sùúrùlérè mọ́ àfi Ọlọ́runṣògo; bí ṣọ́ọ̀ṣì ṣe ń pọ̀ sí i ni ìwà burúkú ń pọ̀ sí i; Wòlíì èké kún ìgboro; ọmọ kò gbọ́ tòbí mọ́; òṣèlú ò lóòótọ́; ìjọba ń purọ́; ọ̀dọ́ ò ríṣẹ́ ṣe; bàbá ń bọ́mọ rẹ̀ ní àjọṣepọ̀; ajínigbé gbòde; adigunjalè kò jẹ́ ká sùn wọra; aṣòògùn owó pọ̀ lóde; alákatakítí ẹ̀sìn fẹ́ gbàjọba àti bẹ́ẹ̀ bẹ́ẹ̀ lọ.

## 4. Kí ni a lè ṣe?

Lóde òní, ìhà tí a kọ sí àṣà wa fẹ́ àtúnṣe àti ìtanijí. Àwa tí a sì jẹ́ olùkọ́ èdè yìí ni a ní iṣẹ́ tó pọ̀ láti ṣe lórí èyí. A níláti tẹra mọ́ jíjẹ́ agbátẹrù àṣà wa. Èyí ni ọ̀kan lára iṣẹ́ tí a gbà gẹ́gẹ́ bí olùkọ́ èdè yìí tí a sì gbọdọ̀ mú lọ́kùn-ún-kún-dùn. Ojúṣe wa ni láti jẹ́ kí àwọn Yorùbá mọ̀ pé èdè Yorùbá sísọ ṣe pàtàkì nítorí pé èdè ní í ṣe okùnfà àṣà. Láìsí èdè, kò lè sí àṣà. Àwùjọkáwùjọ tó bá sì sọ èdè rẹ̀ nù sọ àṣà rẹ̀ nù; bákan náà ni ó sọ ohun ìdánimọ̀ rẹ̀ nù. Kò sí èdè kan tí ó ju ọ̀kan lọ nínú èdè bí i ẹgbẹ̀rún mẹ́fà àti ẹgbẹ̀rin tó wà láyé. Gbogbo èdè yìí ni Ọlọ́run dá tí ó sì gbọ́. Nítorí náà

èdè ni ọ̀pákùtẹ̀lẹ̀ fún àṣà. Orúkọ èdè àwùjọ kan ní a fi ń perí àwọn ènìyàn àwùjọ náà àti àṣà wọn. Yorùbá gbọ́dọ̀ gbé èdè wọn lárugẹ bí àwọn orílẹ̀-èdè mìíràn bí i Japan, India, China, àti bẹ́ẹ̀ bẹ́ẹ̀ lọ.

Gẹ́gẹ́ bí òbí a níláti bẹ̀rẹ̀ sí kọ́ àwọn ọmọ wa ní èdè àti àṣà Yorùbá. *Ẹyin ní í di àkùkọ*. Àwọn ọmọ wọ̀nyí ni ọjọ́ ọ̀la orílẹ̀-èdè wa. Bí a bá sì ti fi àṣà ọmọlúwàbí kọ́ wọn, ó dánilójú pé wọn yóò jẹ́ aṣaájú rere, àwùjọ wa yó sì dára torí pé *Bíbí ire ò ṣe é fowó rà*. Lára ohun tí ó ba Nàìjíríà jẹ́ ni àwọn olóṣèlú wa tí wọn kò ní àǹfààní àtikọ́ ìwà ọmọlúwàbí tí ó yẹ kí àṣà ti kọ́ wọn. Gẹ́gẹ́ bí Ìṣọ̀lá (2013:5) ṣe sọ òṣùwọ̀n ọmọlúàbí ni ogún ńlá tí àtìrandíran ọmọ Yorùbá jẹ́, ó sì yẹ kí a máa fi lé àwọn ọmọ wa lọ́wọ́, kí gbogbo ayé lè jẹ ogún rere náà.

Àwọn tó ń ṣe ètò ìjọba gbọ́dọ̀ wá nǹkan ṣe sí ètò ẹ̀kọ́ ilẹ̀ wa tó ń fẹ́ àtúnṣe. Láti ìpìlẹ̀, ilé-ìwé alákọ̀ọ́bẹ̀rẹ̀ ni nǹkan tí wọ́ wá; *Amúkùn-ún ẹrù rẹ wọ́* ni ètò ẹ̀kọ́ wá jẹ́. Ohun tí ìwé ìlànà fún ètò ẹ̀kọ́ ilẹ̀ Nàìjíríà (National Policy on Education) sọ ní pé èdè abínibí tàbí èdè àdúgbò àwọn ọmọ ní a gbọ́dọ̀ lò fún ìdánilẹ́kọ̀ọ́ fún ọdún mẹ́ta akọ́kọ́ ní ìlé-ìwé alákọ̀ọ́bẹ̀rẹ̀ kí a tó bẹ̀rẹ̀ sí lo èdè gẹ̀ẹ́sì láti ọdún kẹ́rin. Sùgbọ́n báwo ni àgbékalẹ̀ ìlànà tí kó bá ṣe wá ní àǹfààní yìí ṣe rí? Ìjọba kò kọbiara sí àmúṣe ìlànà yìí. Gẹ́gẹ́ bí Fafunwa (1989: 12) ṣe sọ, lára àǹfààní tí àmúṣe ìlànà yìí ò bá fún wa ni:

i) yóò fún àwọn akẹ́kọ̀ọ́ ní ẹ̀kọ́ tó yè kooro nítorí pé wọn yóò ní àròjinlẹ̀ tó múnádóko nínú èdè abínibí wọn.

ii) yóò kọ́ àwọn èwe wa ní àṣà abínibí wọn èyí tí yóò jẹ́ orísun tí ó lágbára fún ìlọsíwájú àti àlàáfíà orílẹ̀-èdè wa.

iii) yóò jẹ́ ọ̀pákútẹ̀lẹ̀ fún ìdàgbàsókè iṣẹ́ ìmọ̀ ẹ̀rọ tiwa-n-tiwa (development of our own indigenous technology).

Dípò tí ìjọba ò bá ṣe èyí, ńṣe ni wọ́n tẹpẹlẹ mọ́ kíkọ́ èdè àjòjì. Ìjọba Abacha tilẹ̀ tún sọ èdè Faransé di ọ̀kan lára èdè tí ó yẹ ká fi máa ṣe ètò ìjọba. Lára ìdàrúdàpọ̀ tí ìjọba tún mú wá ni ìyípadà ètò ẹ̀kọ́ lóòrèkóòrè: 6-5-4; 6-3-3-4; 9-3-4; Ìjọba kò mèyí tí yóò ṣe. Èyí sì ń fa ètò ẹ̀kọ́ wa sẹ́yìn.

Àwa tí àwọn olóṣèlú ń ṣèjọba lé lórí náà kò gbọdọ̀ dákẹ́ títẹ̀ ẹ́ mọ́ wọn léti ọ̀nà tí orílẹ̀-èdè wa yó fi dàgbàsókè lọ́nà tí ayé yó fí dẹrùn tí àlàáfíà yó fi jọba tí ààbò tó péye yó fi wà. A gbọ́dọ̀ kópa nínú ìlú ṣíṣe ní ọ̀nà tí àwá mọ̀. Òwe Yorùbá sọ pé:

i) Ifá ní ká jọ wò ó; mo ní ká jọ wò ó; ohun tí a bá jọ wò gígún ní í gún.

ii) Ò ń wòmí, mò ń wò ọ́; ta ní ṣeun nínú u wa?

Fún àṣà Yorùbá, èrò tèmi ni pé kò lè parun, *ẹpọ̀n àgbò ń mì ni kò ní já*. Ṣùgbọ́n àwa tí a jẹ́ agbátẹrù èdè náà ní ìṣẹ́ tó pọ̀ láti túbọ̀

gbé àṣà náà lárugẹ. A dúpẹ́ fún àwọn Gómìnà, tí ó ní ìfẹ́ èdè àti àṣa Yorùbá, tí Ọlọ́run ń fún wa ní ilẹ̀ Yorùba lọ́wọ́lọ́wọ́ báyìí. Pẹ̀lú akitiyan wọn àti àwọn olùfẹ́ èdè yìí yòókú ọjọ́ iwájú èdè Yorùba yóò dára. Yorùbá bọ̀ wọ́n ní: Ìgbà ò lè di ìgbà òyìnbó ká fàbúrò ẹni ṣaya

## 5. Ìkádìí

Nínú iṣẹ́ yìí, a ti ṣe àgbéyẹ̀wò ohun tí àṣà, pààpàá ti Yorùbá, àti ìṣèlú dálérí. A ti rí ìbáṣepọ̀ tó wà láàrin àṣà àti ìṣèlú. Bákan náà ni a ti rí i pé àṣà ni ọ̀pákùtẹ̀lẹ̀ fún ìṣèlú àti ààbò tó dáńgájíá. Ìwà àti ìṣe Yorùbá ni àṣà wọn ń ṣàfihàn. Ohun tí ó sì ṣe pàtàkì jùlọ nínú àṣà Yorùbá ni ìwà ọmọlúàbí èyí tí ó jẹ́ ògo ìran Yorùbá. Ohun tí a fí ìdí rẹ̀ múlẹ̀ nínú iṣẹ́ yìí ni pé bí àwọn tó ń ṣe ètò ìjọba, tí wọ́n n darí ìlú bá jẹ́ ọmọlúàbí tí ogunlọ́gọ̀ ará ìlú bá sì gbé ìwà yí wọ̀, ìdàgbàsókè àti àlàáfíà yóò jọba ní ìlú.

## Ìwé ìtọ́kasí


Abímbọ́lá, W. (1977). *Ifa Divination Poetry*. New York: NOK Publishers

Àjàyí, A. (2005). 'The Concept of Culture' in Àjàyí (ed.) *African Culture and Civiliation*. Ìbàdàn: Atlantis Books. pp. 1-11.

Fáfunwá, A. (1989). *Education in Mother Tongue. The Ife Primary Education Research Project*. Ibadan: University Press.

Fálétí, A. (1972). *Baṣọ̀run Gáà*. Ìbàdàn: Oníbọnòjé Publishers.

Federal Government of Nigeria (2004). *National Policy on Education* 4th Edition. Lagos: NERDC Press.

Ìṣọ̀lá, A. (2010). *Making Culture Memorable: Essays on Language, Culture and Development* Ibadan. Hope Publications

Ìsọ̀lá, A. (2013) Kín ni a fẹ́ẹ̀ máa fi èdè Yorùbá ṣe? *Ìdánilẹ́kọ̀ọ́ Ayẹyẹ Ìkẹ́kọ̀ọ́gboyè Kẹrin.* Adékúnlé Ajásin University, Àkùngbá-Àkókó, Ondo State, Nigeria.

Ògúndèjì, A. (2006). '*Ojú Ọjà:*A Socio-Commercial Portrait of the Traditional Market-Place in Yorùbá Plays' *Journal of Yoruba Studies Association of Nigeria* 3 (2). pp. 1-14.

Ògúndèjì, A. (2009). 'Èdè Yorùbá gẹ́gẹ́ bí ọkọ̀ tí a fi ń tu ìwà ọmọlúàbí gúnlẹ̀ sébùúté ayọ̀ láwùjọ'in Ògúndèjì, A. and Àkàngbé, A.(eds.) *Ọmọlúàbí: Its Concept and Education in Yoruba Land*. Ibadan: Ibadan Cultural Studies Group.

Ògúntómisìn, O. (2002). "Power-Politics in Old Oyo Empire, 1754-1796" in Ògúntómisìn, G.O and Àjàyí, S. A. (eds.) *Readings in Nigerian History and Culture, Essays in*

*Memory of Professor J.A. Atanda*. Ibadan. Hope Publications Ltd.

Ọdúnjọ, J. F. (1961) À*kójọpọ̀ Ewì*. Ìbàdàn: Longman Nigeria Ltd.

UNESCO, 2002, *Cultural Diversity Series No. 1*.